**Lakaye Oro**

Bi orișirași okunrin ti po laiye, beni awon obinrin jabura-ta bi apa obinrin ti wa beni okunrin oni-na-kuna wa pelu Șugbon șora ki o ma se fe onije-kuje obi-nrin, abije womu wo-mu wombiliki wob-iya Onirunru ni așo alagemo.


# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE „DE„ OKUNKUN PARADA.


**EYI TI MBO**

IROHIN IMOLE:- ti mbo yio kun fun oro nipa bi o tișe le toju ile re ti o fi ni lati wa ni mimo lai ko si ni idoti, ti a o si ma gbe pelu alafia lati owo:- Onișegun Irohin Imole, pelu Itan Oba ti o ni ori eiye ati omo re ti o ni irun Ide.


VOL. V No. 312 MONDAY JANUARY 15 — JANUARY 21 1962 KOBO MEJI (2d)


# Awon Egbe Oluko ile Naijiria nfe Ojogbon Aiye to le so Eedu di Așo wiwo

EKO:- AWON AWUJO EGBE OLUKO TI O MBE NILE NAIJIRIA ȘE IPADE PATAKI KAN NINU EYITI NWON ȘE IPINNU PAPO WIPE, KI NWON KE SI IJOBA ALAPAPOSE WIPE KI O KOWE SI GBOGBO AWON OJOGBON ILE AIYE TI O MBE NI ILE NAIJIRIA KI NWON WA FI OGBON WON HAN BI NWON TIȘE LE SO EEDU OKO DI AȘO TI A NWO.

Awon egbe yi tun yan awon enia pataki melo kan lati fi oju si ișe ati eto ti a nșe ninu ile eko giga University ti ile Hausa, nitoripe ile eko na yio tun pese aye sile nibiti awon Oluko yio ma ri ișe se.

Nwon tun șe igbimo wipe o to, o si ye wipe ki Ijoba Alapapose bere lati ma fun awon Oluko ni e b u n eko olofe, ki nwon le ma lo f u n ilosiwaju eko.

Ati wipe yio je ohun ti o suwon bi Ijoba ba le ma gba awon Oluko lati ile Ajeji wa, Nitoripe a nfe ilosiwaju eko n i n u ede Faranse ede Griki, ede Larubawa, ede Heberu ede Jamani ati ede Latin.

**EDEGBAJI ENIA PADANU EMI WON NILU PERU.**

Irohin ti a tun gbo ni wipe ni abule kan ti o wa ni egbe oke nla kan nilu Peru, efufu nla kan dide o si fe oji lile, to bo ti okuta nla kan ti o wa ni tente ori oke na gegebi okuta O l u m o, ni E f u f u și nidi, o si yi gbiri gbiri lati oke giga na wa sile. Awon enia ti o ngbe abule na to egbaa merin (8000) iye awon ti okuta pa na je egberun meta, laiko ka awon omode ati Arugbo.

## Omo Olola Adesoji Aderemi gbeyawo Arede nilu Oyinbo



Eniti a nwo ninu aworan yi ni Omoba obinrin Ile-Ife ti o nje Fowotade Aderemi, omo bibi inu Alaiyeluwa Olola Adesoji Aderemi Oni ti Ile Ife, to nșe Gomina Ipinle Iwo Orun ile Naijiria ti o lo fun Ilosiwaju eko ni ilu Oyinbo on ni a nwo yi nigbati o te owo bo iwe ni Kotu fun Odomode kunrin kan ti nwon npe Joseph Olushoga ti o le ko ișe nipa oro nilu Oyinbo.

**Imototo fun ile re Lati Owo:- Onisegun Irohin Imole yio bere si jade lati Ose to mbo**

ORO **OLOTU**

## Ipade gbogbo olori awon Oselu ile Afirika nilu Fko

Opolopo awon Asoju lati ilẹ Afirika ni yio de si ilu Eko fun ipade ti awọn Olori Oṣelu ilẹ Afirika yio se ni ipari oṣu yi nilu Eko, o tọ o si yẹ ki a ba awọn Alasẹ wa sọrọ. Gẹgẹ bi awa tiṣe jẹ Oniwe Irohin kan ni ilẹ Naijiria ti a si tun jẹ alagbonandun fun awọn e n i a, iṣẹ wa si ni lati ba awọn Olori Oṣelu ilẹ wa sọrọ isiti, idi rẹ si ni a se fi ọrọ ipade awọn Olori Oṣelu ilẹ Afirika se ẹsin ọrọ wa ti ọsẹ yi.

Ọrọ wa si ẹnyin O l o r i Oṣelu wa nipe ninu ipade yi, ẹ jọwọ ẹ ba wa sọ awọn ohun ti o njẹ wa niya fun awọn alagbara A i y e. A bẹ ẹnyin Oṣelu wa, ki ẹ fi tọkantọkan ṣiṣẹ nyin, ki ẹ si fi ọkan awa enia balẹ. Ni sinsin yi agbara ati aṣẹ mbẹ lọwọ yin. ṣugbọn ẹ lo si ọna ti o tọ ati ti o yẹ, nitori gbogbo ohun ti ẹ ba ṣe s i l ẹ loni, bi ọmọ yin ko jẹ nibẹ, ọkan ninu ẹran a r a nyin mbọ wa jẹ nibẹ. Ẹ ṣe rere lasiko ti yin yi o.

Ninu ipade yin, ẹ sọrọ ti yio fa ire fun gbogbo enia Naijiria, ẹ ma ṣe sọrọ ti yio mu ipalara wa fun wa, nitori a wa na sẹ n k u r o ni ọmọdọ ninu Ominira, a ti ni abure lẹhin, ẹ ma ṣe jẹki wọn tun ga ju wa lọ, eyi nipe, ki awọn ilu ti o gba Ominira lẹhin wa m a ṣ e ga tabi ki wọn male ni ilọsiwaju ju wa lọ, ẹ jẹki o jẹ pe ilu wa ni wọn yio ma n ọ g a wo bi asiwaju awọn ilu ti o sẹṣẹ di Ominira labẹ asia Gẹsi.

Ẹnyin Oṣelu wa ẹ tun bọ ma wa i r e fun ilẹ wa, ẹ mura si i ṣ ẹ nyin, ẹnyin Olori Oṣelu ti ẹ nlọ si ipade na, ẹ sọrọ ti yio gbe ilu wa ga ti yio si fa ire fun gbogbo enia ilẹ Naijiria, ẹ maṣe doju ti ilẹ wa ninu ipade yi. Oluwa yio ran yin lọwọ, iwaju ni ọpa ẹhiti wa yio ma resi o, Oluwa yio jẹki ipade na jẹ eyi ti y i o mu ilọsiwaju fun ilẹ wa ni asiko Ominira wa yi o.

## IWE SI OLOTU

### Wa, be wa wo ni Iwo Orun Olola Dokita Nnamdi Asikiwe

Lati igbati Dọkita Asikiwe tiṣe Gomina Agba ilẹ Naijiria o ti bẹ ipinlẹ Ila Orun wo bi igba mẹrin. o ṣẹṣẹ de lẹnu lọlọyi fun abẹwo ọjọ mẹrindinlogun lati Ipinlẹ Ariwa Naijiria ni.

Ṣugbọn si iyalẹnu mi koiti wa bẹ Iwọ Orun Naijiria wo rara, Dọkita Asikiwe sọ wipe on yio lọ si Iwọ Orun, ṣugbọn o di igbati o ba pada de lati Oke Okun, ṣugbọn gẹgẹbi ileri rẹ koiti mu ṣẹ rara.

Nitorina mo fi tọwọ tọwọ fi iwe mi yi pe Ọlọla Dọkita Nnamdi Asikiwe pe ki on wa bẹ Iwọ-orun wo laipẹ ọjọ, ki o wa wo ohun ti a nṣe.

Emi ni

L. A. AKINTUNDE

IGBO-ORA

## Egbe Ifelodun (Agba) Ajasse Ipo se Ajodun Kerin

Irohin ko to afojuẹa ni ti Ajọdun alarinrin Kẹrin ti Ẹgbẹ Ifẹlodun Ajaṣẹ Ipo ṣe ni ile Alaga M. O. Dende ti 57A, Oroyinyin Street, l'Eko, Gere agogo meje arọ titi di agogo mẹsan alẹ, gbogbo ẹsẹ awọn ọmọ Ẹgbẹ ti pesẹ, ti ojẹ wipe aye ko ti lẹ si lati joko, dipo ti ẹlomiran fi joko nilẹ. Gbogbo Ẹgbẹ duro fun wakati kan ki Alufa ti yio se Adura fun ti Ajọdun to de lẹsẹkẹsẹ ti Alufa de, Oberẹ si Kewu ni orisirisi adura titi o fi di agogo Mẹrin Irọlẹ.

Ni agogo marun Ọjọyi tise ọjọ 7/1/62, gbogbo ọmọ Ẹgbẹ ti lọ parọ aṣọ wọn ti Olukuluku mu Ewu Olowo Iyebiye bora ti nwọn si njo pẹlu awọn Oni Tepu Rikọdin ti wọn Gbajumọ (Famous T a p e Recording) Gbogbo awọn Ojulumọ l'ọkunrin l'Obinrin fi ẹsẹ pa Ijo na titi di agogo mẹsan alẹ.

Ọgbẹni M. Owolarafẹ ti nse Alaga Ẹgbẹ yi fi tayọtayọ dupẹ lọwọ awọn alabẹṣẹyẹ, ati Ojulumọ ti nwọn na Owo ọpọlọpọ ni ọjọ yi, o si fi jijẹ ati mimu tẹ ọpọlọpọ enia ti o wa ni ọjọ yi lọrun, Gẹgẹbi ati manse ni Ọdọdun awọn ẹlomiran ti ko lerin ni ki nwọn gbe on wa woran ni ọjọ yi.

Adura Ọdun titun Ọlọrun Ọba ti ofi Ọdun yi se oju gbogbo wa yio jẹ ki a le se ọpọlọpọ rẹ ni ọdọdun.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJỌ

## Jagunjaguu ile Naijiria kan gbeyawo [arede nilu Oyinbo



Eniti a nwo na ni Lieutenant Mobolaji Johnson, ti iṣe ọkan ninu awọn ti o gba ẹbun ẹkọ Ọlọfẹ lọ si ilu Oyinbo lati kọ iṣẹ Jagunjagun ni Royal Military Academy ni ilu Sandhurst. Ninu agọ wọn lo wa nigbati o fi ọwọ kọ Iyawo rẹ lọwọ, ti o si ya aworan yi On lo gbe Ọbafunmilayọ ọmọ Ọgbẹni Aganga Williams ni Iyawo.

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Abayori Ibere fun awon omo egbe Imole Aiye

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE TI A BERE LỌWỌ AWỌN ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE NINU IWE IROHIN IMỌLẸ TI ỌJỌ ỌDUN KERESIMESI

Ninu gbogbo awọn ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye, awọn enia diẹ ni a ri ti o dahun ibere na, itiju nlanla lo si jẹ fun wa lati ri pe laduru gbogbo bi ọmọ ẹgbẹ ti pọ to ki o wa jẹ pe awọn enia mẹfa ni o dahun ibere na, kişe ohun ti o dara rara, nitorina a bẹ yin ti ẹ ba ti ri ibere kan ti a ni ki ẹ dahun, ẹ jọwọ gbogbo ọmọ Ẹgbẹ ni a nfẹ, ki o ma dahun rẹ, kişe pe, ibere yi wa lasan bi koşe lati fi ọgbọn kun ọgbọn pẹlu imọ rẹ.

EYI NI AWỌN ỌMỌ TI A RI IDAHUN WỌN GBA

Ẹni akọkọ ni:- Peter Adeniyi (No. 25, ọmọ ẹgbẹ)

ẹni keji ni:- Karima Atọlani (No. 35, ọmọ ẹgbẹ)

ẹni kẹta ni:- Tajudeen Adeboun (No. 49, ọmọ ẹgbẹ)

ẹni kẹrin ni: J. Oseni Ọmọmeji (No. 203, ọmọ ẹgbẹ)

ẹni karun ni:- Abdullahi Awelenje (No 1, ọmọ ẹgbẹ)

ẹni kẹfa ni:- Emanuel Ọlawale (No. 10, ọmọ ẹgbẹ, itan ni kan ni eleyi dahun.)

Awọn enia marun iyoku dahun itan ati ibere nipa Jesu, nwọn gba şugbọn ko si ẹniti o gba ibere kẹrin (No. 4) ninu gbogbo wọn.

EYI NI IDAHUN AWỌN IBERE NA.

1 A bi Jesu si Bẹtilẹhẹmu Judia ni ibujẹ ẹran 2 Awọn Amoye mẹta lo wa bẹ Jesu wo. 3. Nkan mẹta ti wọn fi ta Jesu lọrẹ ni Wura, Turari ati Ojiya. 4. A ngbadura si Ọlọrun lati le fi har Ọlọrun pe a gbagbọ, on si Mbẹ. 5. Ẹniti o ma npin Ẹbun fun awọn ọmọde lasiko Odun Keresimesi ni: "Baba Keresimesi" eyiti wọn npe ni ede Oyinbo pe (Father Christmas)

Itan:— Egbọn ni o lagbara ju, nitori bi ko ba si ti rẹ ni Iya nwọn ko ba ku. Mo ki gbogbo ẹnyin ti ẹ dahun ibere na. Oluwa yio tun bọ ma fi imọ kun imọ yin, Ọpolọ yin ko ni daru mọ yin lori, Oluwa yio ran gbogbo wa lwọ o. Amin. ẹ se o

AKỌWE AGBA

## Enia ni koni ki a gbon, enia ni si ko ni ki a go

Lati Ọwọ:— Abdullahi Awẹlẹnjẹ
No. 1, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Ni igba atijọ ẹiyẹ Akọ pẹlu Ehoro jijọ nşe ọrẹ, ọrẹ wọn yi pọ tobẹ ti o jẹ wipe gbogbo awọn ẹranko pata ati ẹiyẹ ni a wa iru ọrẹ bẹ ti larin wọn. Korikosun ni wọn, ti wọn si ma nlọ jẹun nile ara wọn, nigbati o di ọjọ kan ni asiko ti iyan si mu, ni ẹiyẹ Akọ ba şe aşe kekere kan, o si lero wipe ọgbọn wo ni on le da si ti onjẹ kekere yi yio fi to on jẹ yo, o si pinnu lọkan ara rẹ wipe, on yio lọ wa akoregbe, ẹşe eyi o si fi onjẹ na sinu rẹ, o ba ransẹ lọ pe Ehoro ki o wa jẹun nigbati Ehoro de o duro titi, o poyi titi, nigbati o şe o wi fun ọrẹ rẹ wipe o di gba Akọ si fi inu da lohun, choro si pada lọ.

Bi Ehoro ti dele, o wa onjẹ sẹnu, bi o si ti di ọjọ keji, on na şe ase, o ranse lọ pe ẹiyẹ Akọ, o si gbe onjẹ na sinu awo pẹlẹbẹ, nigbati Akọ de, o gbẹnu sinu awo ko le ri onjẹ jẹ, ni Ehoro ba bẹrẹ si rẹrin, nigbati o si bi Ehoro bayi wipe ki lo fa ti o fi şe eyi fun mi? Ehoro si wi fun pe enia ni kọ ni ki a gbọn, enia ni si kọni ki a gọ.

## Orc nipa awon Onitete tabi awon Onibuga

Lati Ọwọ:— Karimu Atọlani.
No. 35, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE

Olotu jọwọ gba mi layẻ lati sọrọ diẹ fun awọn ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye nipa awọn Onitẹtẹ tabi awọn Onibuga ti o wa ni Ọpopo Oroyinyin ati Jankara ni ilu Eko ni ọjọ Satide (Saturday) ti işe ọjọ kẹfa oşu kini ọdun yi (6/1/62) nigbati mo nkọja lọ ni mo ri ọpọ enia ti oduro, ni emi na ba ya nibẹ, nigbati mo debẹ, ni ọkunrin kan ba fi Pọun marun (£5) ta tẹtẹ, nigbati o si tu kini ti wọn di sinu pepa, o ba Şọọki ati Buledi ninu rẹ, ni Baba ba bẹrẹsi sọkun, o ni owo ti on fẹ fi ra iwe fun ọmọ on ni owo yẹn, o si bẹrẹ si bẹ awọn ọkunrin na, wọn si da lohun pe awọn ko sa ti ọwọ bọ lapo, nigbati Ọlọpa si de, nşe ni gbogbo wọn salọ nitorina gbogbo awọn ti o fẹ ra nkan ni Eko ni wọn ti mu ni igan tan o.

Nitorina ẹ ba wa sọ fun awọn Ọlọpa pe, ki wọn ma fi wọn lọrun silẹ o, nitori wọn nba ilu Eko jẹ fun wa ipari ọrọ mi re o, ipade wa bi oyin o. Mo ki gbogbo ẹnyin ọmọ ẹgbẹ patapata pe ẹ ku alaja ewu Ọdun ki Ọlọrun jẹki ọpọ rẹ soju ẹni gbogbo wa o. Amin.

## Olotu atijo ba Olotu titun soro



Aworan oke yi ni ti Olotu akọkọ Dr Eisenhower, ati Olotu titun John F. Kennedy nigbati wọn lọ se ipade ninu ile ti Ijọba ilẹ Amerika kọ fun Olotu ti wọn npe ni (White House) Ile Funfun, ni ọjọ kẹfa oşu kini ọdun tokọja, nigbati wọn fẹ gbe iwe işẹ akoşo Olotu le Kennedy lọwọ, nitori on ni Olotu titun fun ilẹ Amerika. Lẹhin ipade yi ni awọn Olotu mejeji si jumọ sọ wipe ilẹ Amerika yio ma wa alafia ati Ominira fun gbogbo enia.

Read IROHIN IMỌLẸ every week, It is Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Picture and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

IROHIN IMỌLẸ

# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 12)

Lati Qwọ:- SIMEON ADE. FATOKI (London)

Ona Ilu awọn afọju yi ni mo tun gba pada bọ mo si tun ya ki wọn me lo ọjọ melo kan lọdọ wọn me si kọ wọn ni ọpọlọpọ ọgbọn, Nigbati mọ kuro nibẹ mo ya kiri ọpọlọpọ I l u miran ti mo nfi ye wọn ohunti Ọlọrun fẹ ati eyiti ko fẹ. Mo fi nye wọn w pe ti enia ba fi nkan meji pẹlu nkan marun ni onjẹ yẹ, mo kọ ọpọlọpọ ilu ti o fi jẹpe nigbati oku to ogun Ibuṣọ ti mo ma de Ilu mi ti mo si ti kọ Iwe sile pe mo mbọ ni gbogbo wọn ti mura silẹ de mi. Iwọ ọrẹ mi ẹnu ko, gba irohin ni ọjọ ti mo de ilẹ, wọn wa gbe Ayẹkẹlẹ t la kan pade mi ni Ibuṣọ kejila emi ati awọn obi mi iyawo ati awọn ọmọ mi ni ajoko sinu rẹ ti wọn si ki mi kabọ, won gbin ododo si gbogbo oju ọ n a lọ, ti wọn si se gbogbo Ilu li ọṣọ nla.

Nigbati mo de ọdọ Ọba ti mo si duro lati ki ọlọpa kan si ilẹkun ọkọ fun mi ni mo bọ silẹ, dipo ki ndobalẹ fun Ọba se ni o na ọ w ọ si mi pe ki gba on lọwọ ki nma ṣe dọbalẹ fun on rara. Nigbati Ọba papa sọrọ ninu erọ gbohungbohun o ni " Inu mi ati ti awọn ara ilu yi dun lati pade rẹ, ati pe lati ri pe iwọ ti o kọkọ lọ si igbo ailopin na pada de pẹlu ayọ, iwọ si ti sa gbogbo ipa rẹ lati fi ọgbọn si ori rẹ, o ti di ọlọgbọn aiye ati ọlọgbọn enia. O ti gbe orukọ ilu rẹ, enia rẹ, obi rẹ, ati ile rẹ yọ ni aiye yi.

Mo ki ọ pe, o kabọ o bayi ni Ọba sọ ti o dakẹ mo dide si mo ki ni ẹ ku ile o ṣe dada ni mo ba yin o. Ṣe enikeni ko gbon ao, inu mi dun pupọ lati wa pẹlu yin loni, oni ni o di oṣu mẹfa ati ọjọ kẹdọgbọn ti mo ti kuro ni ilu yi, ti mo si gba igbo ailopin lọ kọ ọgbọn.

Mo ti fi oju ri ọpọlọpọ idanwo ṣugbọn nikẹhin mo ri ohunti mo le sọ, mo fẹ ki ẹ mọ wipe ko si ẹniti ko ni idanwo tabi wahala tirẹ ni ile aiye lati gbọ mo fẹ ki ẹ mọ wipe enia ko gbọdọ mu aiye ni ẹlẹ rara.

Ranti pe igbesi aiye ti ko ba ni wahala ninu igbesi aiye lasan ni, mo fẹ ki onikaluku t ẹ r a mọ iṣẹ rẹ, ohunti ọwọ rẹ ba ni sise, fi agbara rẹ se ja lati ran ilu rẹ lọwọ.

Iwọ ọmọde ranti pe oni iṣẹ nla lati se ma si se se ọlẹ rara. Iwọ ti oba ni owo fi owo rẹ mọ ẹbi enia rẹ, ati Ọlọrun Oba ti o fi fun ọ, bẹsini iwọ ti oni Ọla ranti pe Ọlọrun lo fun ọ mase lo ni Ilokulo bi omi ojo. Ẹnyin ọmọ enia ẹ maṣe huwa kiwa si ẹranko, ranti pe Ọlọrun ti ofun ọ, ni ọgbọn le gba lọwọ rẹ bi oko ba lo dada, o si le sọ ẹ di ẹranko ti oba lo ni ilokulo, iwọ ọmọbinrin fi iwa Agbere silẹ bẹna se ni i w ọ ọmọkunrin. Mo ti ri ọpọlọpọ irisi ni oju ona jowọ ipokipo ti oba wa jẹki otẹ o lorun, Iwọ ti o wa ni ipo Eku mase fẹ fi agbara wa ni ipo Okete, o dara ki owa ni ipo Eku ki o ma jẹgbadu, ju ọwọ Ọlọrun. Mase gbero lati ba ti ọmọnikeji rẹ jẹ. Ranti Ẹlẹda rẹ ni igba ewe ti owa yi ki o si ma rantipe ole se ohun gbogbo. Bi mo b a ni ki nma sọrọ lọ loni, otipọjulọ ti emi le sọ ṣugbọn emi yio da duro bayi di ọjọ miran, iwọ ti oba nfẹ Imọran le wa ri mi tabi ki o kọ iwe si mi mo si wa lati ran ọ lọwọ nigbakugba. Bayi ni mo sọ ti gbogbo wọn si tuka ti emi na lo si ile mi Ojo kẹrin ti mo de ni wọn fi mi jẹ igbakeji Ọba ati pe lẹhin ọba emi ni mo wa ni ipo re ti igba temi si tu gbogbo Ilu ati Araiye lara. Bayi ni Itan mi yi de ipari mo si ki ẹnyin onikawe yi pe ẹ ku Ijọ mẹta o, Mo ro pe ẹti gbadun itanyi yi dada Mo si ro pe ẹ ti kọ ẹkọ ipa rẹ gan

---

# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi ailowolọwọ ba nda ọ lamu, biairọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airisese lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nsiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njẹ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mbọ ọ lọkan jẹ ni gbogbo ẹjọ.

Mọ daju wipe diẹdiẹ le kọkọ berẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe. Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWO
16, MỌLEYE STREET
P. O. BOX 166 YABA - NIGERIA

---

# Idanwo fun awon Omo Egbe Imole Aiye

Lati Qwọ:— AKỌWE AGBA.

1. Bi o ba nlọ si ode, ti o si kọja lojude ibiti nwọn nṣe agbẹdẹ. Bawo ni iwọ yio ti ṣe ki Alagbẹdẹ na, kini esi ti wọn yio fun?

2. Bi o ba nlọ loju ọna oko, ti o si ri Akọpẹ kan, tabi Ẹlẹmu kan lori igi ọpẹ, bawo ni Iwọ yio ti ki i?

3. Nigbati o ba pade Iya Alaro kan nibiti o ndaro, bi o ba wipe, Arẹdu o! Iya, bawo ni yio ṣe dahun?

4. Awọn tani a nki bayi wipe Ojugboro! ti o si ndahun wipe, Oriya o!

5. Bawo ni a ṣe nki Onişango, bawo ni o se ndahun? Bi o ba ti le dahun ibere na ki o tete kọ tirẹ ranṣẹ.

---

## MOGBAYI COUGH MIXTURE




Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ orişirişi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nha enia ni ohun, Ikọ ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, I k ọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arẹ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan m i r a n ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi etc.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu, Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jẹ 2/6d' rapọ rẹ jẹ 24/-.)

LILO RE:-

Ọmọ oşu mẹta—Idaji şibi tii kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oşu mẹta si mejila·- Şibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa.- Şibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba ——— Şibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Wholesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6, Balogun Street West
Lagos, Nigeria.
Phone 22515.

34, Docemu Street,
Lagos.
Phone 24247.

---

Ma a ka Irohin Imole

# Ajegboro-dagba nki nyin o!

Mo ki gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ, ẹ ku ọjọ mẹta, Ara ko le bi? ẹ si ku alaja Ọdun Titun Ẹmi wa yio ṣe ọpọ rẹ laiye o.

HA ẸNYIN ABIYAMỌ ETI YIN MELO? ỌMỌKEKERẸ BINRIN KAN MU ỌTI YO NI ILU EKO

Ohun ti o fa ti emi ọkunrin mẹta, a sọrọ bi ẹni mọ tẹlẹ ṣe kọ akọle mi ọsẹ yi bayi ni wipe ẹniti o ba nrin irin kurin loju rẹ ma nri iri kuri, on na lo difa fun emi Ajẹgboro-dagba lọjọ Ọdun nla, nigbati mo wọ agbada ẹtu, ti mo de fila abieti aja ti mo wọ sokoto kẹmbẹ, eyiti iṣe aṣọ awọn Baba nla wa, ti mo wa gbe koko taba mi si ẹnu, ni mo ba nlọ, nigbati mo de adugbo kan ti wọn npe ni Isalẹgangan, mo ri ti wọn ta ẹni ti wọn si tan ina lẹntiriki sibẹ, ti o fi jẹ wipe, nse ni ibẹ dabi ọsan loju mi, mo si bẹrẹ si gbọ ilu, ti ilu na si fanimara, ni mo ba ya sibẹ, mo wọle, ṣugbọn owo ni mo fi wọ ọgba ti wọn ta ẹni si na.

Gẹrẹ ti mo wọ ile, ti mo si joko, ni mo dede wo iwaju mi ti mo si ero, mo lero pe boya wọn nja ni, nitori ija ki pẹ lọwọ awọn ọmọ Eko. ni mo ba dide lọ wo wọn bi mo ti de ibẹ, mo ri Ọmọ kekere Obinrin kan o wọ aṣọ onirun (Woollen) olowo iyebiye, ti o si nta gọgọ kakiri agbo. Ti awọn ero iworan bẹrẹ si nfi ṣe yẹyẹ. Mo bere pe ki ni ohun ti o ṣe e, wọn ni o mu ẹti yo ni, mo lanu, emi ko si le pade mọ, ẹnu si ya mi pe iru ọmọdebinrin arẹwa ti o sẹsẹ wa jaiye lo mu ọti yo bayi ti o si nṣubu lebu ti o nsọ ọrọ ti ko tọ ati eyiti ko yẹ, o si nda ibẹ ru, obinrin ọmọkekere ti ko ga ju ẹsẹ bata mẹrin lọ ni o yo bayi, mo bere lọwọ ara mi nibo lo ti ri owo ti o fi mu ọti bayi.

Njẹ ẹnyin Obi, ẹ ko ha ri oju aiye lode bayi, mo wa bẹ gbogbo ẹnyin Obi, ẹ ma ba awọn ọmọ yin sọrọ ti o le wọ wọn leti, ti wọn ba nlọ si ode, ẹ ma mojuto awọn ọmọ yin daradara, ẹ jẹki apa ati ẹnu yin ka awọn ọmọdebinrin yin dada, ẹ ma ṣe ma gba wọn laye lati da aṣa kaṣa. Iru ọmọ ti o lọ mu ọti yo yi ko bẹru awọn Obi rẹ ni, ẹ mu awọn ọmọ yin daradara, ẹ jẹki wọn ni ibẹru yin lọkan, ki ṣe nipa pe ki ẹ ma na wọn ni mo wi, ohun ti a fi nkọ ọmọ ti o ju ẹgba lọ wa.

Lakotan ọrọ mi mo pe gbogbo ẹnyin Ọmọdebinrin ti o ma nlọ si ile ijo tabi ode, ẹ maṣe ma mu ọti, ko dara fun yin lati igba yi lọ, bi o ba mọ yin lara tan, awọn Ọmọdekunrin yio ma fi ọti tan yin lati ba yin ohun ti ko tọ, ẹ ma ṣe ti iwoyi gbe igba ati arode osi dani, nitorina mo ba yin damọran pe, ẹ ye ma mu ọti, o tete nsọ ni di arugbo, bi ẹ ba nfẹ ki igbesi aiye yin dara, ki ẹnyin na le di ẹni iyi lọla. Iwọ ọmọ ti o mu ọti lọjọ yẹn, jọwọ lọ fi silẹ, ko dara.

Lọsẹ ti o mbọ lagbara Odunmare emi yio tun bẹrẹ si sọrọ nipa awọn ọmọ J. J. ati awọn ti wọn ngba owo ile Ẹkọ wọn lati lọ fi ṣe ọmọ Jaiye Jaiye nile ijo ipade wa ni oyin.

## Alufa ti o nse atunse Iwe Bibeli.



Ẹniti a nwo ninu aworan yi ti Iwe kan wa niwaju rẹ ni ọkan ninu awọn Alufa enia Ọlọrun ti o nyẹ awọn ọrọ inu Bibeli na wo boya asiṣe le wa ninu ile itẹwe ti Oxford, on nikan ni yio ṣe ofin toto adọta ọkẹ na, iṣẹ rẹ ti o si ngba owo le lori nuni.


# KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jẹri wipe ojulowo haunhaun Egbogi gidi ni LEOPILLS, Awa na nlo ni ilu Gold Coast (Ankara) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo orisirisi Egbogi kakiri ilu Naijina.




## Irohin Kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna ni ẹwẹ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia. tọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara wọn jẹ nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atamatase fun iwosan JẸDIJẸDI bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun le fi ọwọ sọya tabi ṣe ileri fun gbogbo awọn ti amodi tabi a san bi Akọ Inarun. Lakuregbe, Ẹjẹ didu lara, Arun Ẹdọki iju, Igbẹsise, tabi Aikẹri Igbọnsẹ dede, Inu rirun nigbakugba Ara wiwo, Ẹsanri, Ẹhin didun, Ojusi san ta'i aiko riran kedere. Kokoro buruku lara, Osi inu Onigbameji. ati orişirişi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia ti wọn ba nlo egbogi LEOPILLS nitorı pe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata.

ṢẸ IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9) Egbogi Leopills:- Igo nla şile mẹfa pere ni, igo kekere şile mẹta pere ni.

Bere ojulowo Egbogi Ominira fun orişirişi amodi ti o ba fe ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores
8, Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone: 22878. ati pẹlu ni ṣọbu ara binrin Mrs C. O. Babajide near Health Office Ibadan ati ni Abimbola Medicine Stores B29 Okeṣha Street, Ilesha Bisale Medicine Stores. British & Foreign Medicene (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET IBADAN N.

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe Ṣọbu ti wọn nta lo gbe ranşẹ lọ ra, bi bẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi orişi omiran fun ọ o, maşe gba rara

# Efi Ododo ye Araiye

Lati Owo- KOLAWOLE

Omo araiye e sora pelu awon Woli eke ti nwon nfi enu didun ati ogbon ori tan yin, lati le fi ye nyin wipe awon moju, Iru isele bayi ni ti Ogbeni Samuel Woli Kogberegbe, nipa oro tio so si inu Iwe Irohin Imole ti ojo Monday, ojo Kejo Osu Kini Odun yi (8/1/62).

Ogbeni eletan na nle fi ogbon ori,ati oro etan re yi oro Olorun ti a ti ko ki on papa to d'a e, ti opolopo en a ti ko ni opolopo igba ti o deyu won ju on gan lo, wipe ki a ma se je eran Elede, padasi wipe, Elede je ohun ti odara ni jije fun olukaluku wa, Ha! Iro g b a a ni eyi je, Olorun ni o t u n ra re so si Lifitiku ori 11, ese 7 wipe a ko gbedo je eran Elede, Bi ogbeni Woli Kogberegbe ba fe lati yi okan gbogbo araiye pada wipe, ki awon o ma je E l e d e , o ye ki o koko se ayipada oro yi ninu Bibeli na.

Ni toto, iwa lesin bi en'a sunmo Olorun ju Jesu papa lo bi ko ni iwa daradara o ti daju wipe ko ni ri Alujanna wo. Sugbon nigbati Ogbeni Woli yi mo bayi, o ye ki o le fi lakaye gbe wipe, eyiti o buru julo ninu iwa ni wipe, ki a s'aigboran si eniti o ba ju wa lo Iberu Olorun si ni ki a pa ofin re mo, eyi de n o le mu wa wo Alujana

Ni idi ai ko gboran ni Olorun fi le Adamu ati Effa (Baba ati Iya nla wa), si ita ninu Ogba (Edeo), ni iqosi nje iru iya wo ni Ogbeni Woli eke yi fe ki Olorun fi je awon ti o nfe yi okan won pada si wipe ki won ma je etan Elede? ni igbati o je wipe ninu ikapa Olorun na ni gbogbo wa si wa.

Olorun so ninu I w e Mimo re wipe enikeni ti o ba fi kun oro Oro Olorun, o fi iponju n'la kun iponju ti o mbo wa ba, beni enikeni ti o ba bu die kuro ninu oro Oro Olorun, o fi Iya nla kun Iya ti yio je Oluwa re.

# Igbesi Aiye mi ninu Igbo Ironu piwada (APA 2)

Lati Owo:- TAJUDEEN A. ADEBOUN.
NO. 49. OMO EGBE IMOLE AIYE

Enyin Onkawe mi lose tokoja mo so fun yin pe e o ma gbo Itumo oruko awon mejeji niwaju.

Itumo APEKUN JOYE NIYI ati idi ti won fi ma npe baba mi be, nigba laelae Igbo kan wa, won a si ma pe Igbo yi ni Igbo E k u n. Ninu Igbo yi kosi Eranko miran n fi Ekun ni won wa nibe, kosi Ode ti o le wo Igbo yi lo se Ode nitoripe awon ekun merin lo wa lona bode Igbo na. Okan wa ni apa Ariwa, ekan ni apa Gusu, okan ni apa Iwo Orun, okan to wa ni apa Ila orun Igbo yi awon Ekun yi wa bi Asona igbo yi, olukuluko awon Ekun ni o ni Omose, nitori igba miran Ija lede ti agbara Ekun yi koni ka onija re awon Omose re gbe nija. Nigbati okan ninu awon Oloye Olode kin ku, awon ti won fe je oye yi po nitorina Oleri Ode Ilu yi fi ase si pe eniti o ba le lo pa Ekun ni Igbo Ekun wa ni yio je oye na.

Gbogbo awon Ode na lo ti gburo Igbo buruku yi, ko si eniti o fe lo ninu won, sugbon Baba mi nikan ni o fe lo si Igbo na, Bab mi mura o fi ese si ona Igbo yi bi Baba mi se ti jade emi na si tele sugbon Baba mi ko mo pe mo te le on a fi igbati o de ibikan ti o wo ehin ni o ko firi mi o si pe mi mo si da lohun nigba yi ni mo to wa gba apo lowo Baba mi ti a si jijo nlo nigbati o se a de Igbo na, sugbon nigbati a ti sun mo Igbo yi ni awon Ekun yi ti ngburo wa ti won si mura sile de wa, Baba mi si fi ewe bora o wo awon Ekun na, o ri wipe won ti mura Ija sile de on. Nitorina on na mura nibe o si jade si awon Ekun na nigbati awon Ekun yi ri Baba mi gogo so won ko ja titi ile fi mo ni, sugbon nko nile rohin fun yin bi Ija na ti to nitoripe Irohin koto afojuba. nikehin Baba mi pa Ekun na, sugbon ogbon ni o lo, ogbon na niyi Nigbati won eja baba mi subulu, o si se bi eniku, Inu awon Ekun yi dun pupo won se bi Baba mi ti ku ni sugbon mo nduro de ohun ti won fe fi Baba mi se, gbogbo won si nlo wo loju wo, nikehin Oga won lo, bi o si ti sun mo Baba mi lati wo bi oku, bi koku ni Baba mi mu ni Egbon o si fi obe la si meji bayi ni Ekun na nja poro Iku.

WO IYOKU NI OJU EWE KEJE

# Oloye Akintola so iye owo ti Omo ilewe giga yio ma san

Awon Onise Irohin bere lowo Oloye Akintola wipe nisisiyi ti o je wipe owo ile eko giga fo soke yi, ki Akintola so fun awon elo ni o le dinku si.

O dahun wipe Ijoba Iwo Orun, nna owo goboyi nipa ilosiwaju Eko ni ipinle yi ni owo ti o po to 43 tabi 45 Percent ati o ti han gbangba si on wipe, awon Oga-Agba ile Eko giga, a tun ma gba owo miran ey ti o nje ki owo ile eko su awon Obi ni sisan.



Nitori idi eyi, Ijoba nfe ponun medogbon lowo Omokunrin ati ponun medogun lodo omo Obinrin fun odun kan, bi nwon ba ti san owo yi isoro ni yio je fun Oluko kan lati tun gba owo miran lowo awon omo ile eko.

Oloye Akintola mbe ninu awon igba moto ti ko ri ona gba koja lo ni buso metala lati Eko lo si ona ilu Shagamu ni ojo Isinmi tokoja.

IJAFARA LEWU

## Ma tan Ara re je mo!

Bi o ba daju wipe "IKO" tabi amodi "IGBAATYA" lo nyo o lenu ti ojo re si pe pupo, ma tan Ara re je mo nipa rira awon "EGBOGI ROBIROBI" ti awon eta kakiri ode nisinsin yi ni owo poku. Won ko lese iwosan "IKO" ti ojo re ti pe rara Sobu kan ti o le ri orisirisi egbogi "IKO" t o daju, atamatase ati ajebina lati ilu awon Jamani, Faranse, ati itali (Tatanbulu) ra ni igboro Ilu Eko tabi ni Sobu awon ilu Saro ti awon npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

## Nigerian Ports Authority

CHANGE OF PRIVATE MAIL BAG NUMBER

With effect from 1st January, 1962 the Private Mail Bag Number of the Nigerian Ports Authority, in Lagos has been changed (from 2588) to 12588

All future correspondence for the Authority in Lagos should read:

**Nigerian Ports Authority,**
Private Mail Bag No. 12588,
LAGOS

*BAYO KEHINDE*
*Secretary to the Authority*

N. P. A. Notice. No. 673
8th January, 1962.

## Omo Ojikutu gbeyawo nilu Oyinbo



Ọgbẹni Bashiru Ojikutu, ti o jẹ ọkan ninu awọn Akọwe Ọba nilẹ Naijiria lo gbe Omidan Yusufu ni Iyawo arede nilu Oyinbo lọhun.

Ninu aworan yi ni a le ri Bashiru Ojikutu Ọkọ Iyawo yi nigbati o nfi oruka si Iyawo rẹ lọwọ.

### IMỌTOTO FUN ILE RẸ

Lati Ọwọ:- ONIṢEGUN IROHIN IMỌLẸ

Oniṣegun Imọtoto yio bẹrẹ si sọrọ sinu Iwe Irohin Imọlẹ gẹgẹbi a ti le ṣe Ile wa ti ko fi ni si n k a n b'arun, Ọrọ rẹ yio bẹrẹ lati Ọsẹ to mbọ ninu Iwe yi.

### OBERE LATI OJU EWE KẸFA

Awọn Ẹkun yoku ti salọ bamubamu, Nigbayi ni Baba dide ti ọkan emi na si balẹ dada, asigbe oku Ẹkun na wa si Ile pelu ayọ ati Idunnu ni afi yọ si Ilu wa nitoripe ọpọlọpọ lo ro pe ako le pada de mọ.

Ni ọjọ Ọyẹ yi Gogoso ṣugbọn awọn to dun mọ ko to awọn ti Isu nbi e nikojẹ ki Baba mi pe lori oye yi ju bẹ lọ o ẹyin olukawe mi ẹku kika itan yio ni ọsẹ to nbọ ẹ o ma gbọ itumọ orukọ Iwin na ẹeiti orukọ rẹ njẹ "Onisuru koni kaba mọ laiye" ati iru ọrọ ti Ẹbọra na sọ fun Baba mi o. Ẹ o ma gbadun mi siwaju si lọsẹ tombọ.

Ẹ jọwọ ẹ ma sai ma ra Irohin Imọlẹ lọsẹsẹ nitori Itan oloyin momọ yi o. Ọlọrun koni fi Ẹmi kukuru jẹ wa biya o. Amin, O digba na o.


BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

## "DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ. Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dokita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ. Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de wọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara ọrẹE-emi (breath) inu ko ba gunlẹ dara ara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣẹ ko "NJẸ" fun wọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daju pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara rẹ ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakugba yio salọ patapata pẹlu

Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WA KEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

OBERE LATI OJU EWE KEJI

Olorun Oba ko nije ki a rin ni ojo ti ebi n p a ona, Asi tun dupe lowo Olotu, ati Osise Irohin Imole fun Ikanlowo ti won se fun wa ni ojo yi, ti won si fi orisirisi Ikaye siwaju alaga wa Oko Oba ko ni sa yi. l'Ese iwaju ni opa Ebiti nre si Amin.

Die ti aye gba lati Daruko ni ojo yi ni, Alufa Songa Alfa A. Adigun ati Malam Gboyega D. Olatunji ati Y. Dala B. O. Obadoke S. Aiyelabowo Y. S. Balogun S. Adiogbo S. Adigun A. I. Adigun S. K. Agbabiaka S. Larinkoye, ati bebe lo ti aye kosi lati daruko won. Olorun ko fi opo Odun se oju Emi wa l'aiye.

## Akiyesi Pataki

### Sengovan Tablets! Sengovan Teblets!!

SENGOVAN: Tablets: Je ajidewe fun awon agbalagba ati Ilera gegebi omokunrin.

SENGOVAN: Je okan Pataki ti a se iwadi ni ilu Oke re ni ile Jamani lowo okan ninu awon Ojogbon Onisegun Aremo ti ilu Western Germany. Fun are ara eniti ejo ori re to Ogoji si Ogorin odun (40: 80 years.)

SENGOVAN: Je ogun ti o ti wa lojo pipe fun anfani awon Agbalagba Ilu Jamani ki a to se amuwa re si ilu Naijiria. Ajebidan ni ogun yi Irohin ko to afojuba.

Bere. A o ri lowo awon Onisegun (Doctors) Naijiria tabi lowo Alagba Messers HASSAN COMMERCIAL MEDICINE STORES 26' BISHOP STREET LAGOS PHONE: 23746 DIRECTION: 1 to 2 Pills is sufficent for your constitution, if so do not take more pills at one time. SENGOVAN IS FOR YOU.

## MOGBAYI BABY MIXTURE

OLURANLOWO FUN AWON ABIYAMO

MOGBAYI BABY MIXTURE je ogun pataki ti a se ni ase pe fun awon Omode, ati nlo ogun yi fun opolopo odun sehin pelu idaniloju fun Awon ise tibi tibi ti o ti nse.

MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi to dara fun iekona, iko, otutu A i p e r i, Osi Omode, jedijedi, kokoro ori Omode. O dara fun omode ti ko tete rin ati fun awon aisan miran bebe lo. O nmu omode ko ma nmu fonfon O nmi ki ehin hihu je iro run fun awon omode o nmu ki awon omode tobi, osi nmu won dan ni awo. Enyin Abiyamo, eku afojuba egbogi yi. Aran yin letipe MOGBAYI BABY MIXTURE je egbogi ti ko se mani fun awon Omode I j a f a r a lewu pupo, tete lo ra tire ni le itaja Egbogi towa ni Adugbo re.




Igo kekere re je 2/6d Igo nla je 4 6d

LILO RE:- Sibi kekere lemeta lojumo

*Wholesale Distributors*

A. K KARIMU ANJOLA & BROS

| | |
|---|---|
| 6, Balogun Street West, | 34, Docemo Street |
| Lagos Nigeria | Lagos |
| Phone 22515 | Phone 24247 |

Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 16, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adeniji 51, Tejuosho Street, Suru-Lere YABA.

FUN OWO IROHIN IMOLE ODUN KAN EKO:- Sile Mejo ati kobo Mejo (8/8d Ilumiran ni Naijiria ati Oke Okun:- Sile mejila ati Kobo mefa 12/6d

ONISEGUN IROHIN IMOLE YIO BERE SI BA YIN SORO NIPA IMOTOTO LATI OSE TO MBO.

# Loya Aremu Olusegun gbarede nilu Oyinbo



Ogbeni Olusegun Aremu jo okan uinu awon omo Akoko ti o lo ko ise amofin on lo gbe Omidan Emanueli Olusola ni yawo Arede nilu Oyinbo. Ofi Leke Dayamon si iyawo re lorun, o si tun fi oruka bo lowo tan, ofi apa ko iyawo na lowo bi o si ti nse jade lo ya aworan yi.

BERE OJULOWO EGBOGI WONYI:-

### "Congreve Female Remedy"

Gbogbonse fun Itoju tabi Ajo Obinrin fun Inu rirun Ibadi riro tabi gige nigbakugba, ati orisirisi arun tabi amodi ti o ma nyo Obinrin lenu ni Inu nigbakugba.

### "Collomack"

Egbogi awon Jamani ti o dara julo fun Itanpara, awo ESE lile, Igbado ese ti ki jeki enia le wo bata (Corncure) ati orisirisi arun Ese miran pelu ni

### "Mack-tal"

Atamatase Egbogi awon Jamani fun orisirisi amodi "ETI" riro tabi didun fun omode ati agbalagba bi o ti wun ki ojo re ti pe to yio se iwosan re ni kiakia.

### "Meduprival"

Ojulowo egbogi awon ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ona-ofun, Imu tutu tabi ti o ma nsomi bi ikun nigbakugba, Kelebe ona ofun tabi agbari h ha, amurun ati orisirisi amodi miran gbogbo ti ibere re jo otutu. Bere ti Omode tabi ti agbalagba won yato nipa agbari won ni o

Bere ni Sobu:—

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA
WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OSHOGBO

ATI NI AWON SOBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BOLA